# EKO AKETE.

## IWE IROHIN ỌSỌSẸ.

ỌRỌ IFOJUSUN:—

"EMI YIO FI OHUN TI O NDUN MAKUNNU HAN AWON ALAGBARA, NGO SI JE ALAGBAWI AWON ODI".—W. T. STEAD.

VOL. I. NO. 42. SATURDAY, APRIL 28, 1923. FOURPENCE.

*Editor & Proprietor*:—
ADEOYE DENIGA,
*Office*: 24, Williams Street,
P.O. Box 286,
Lagos, Nigeria.

ASAN-SILẸ NI OWO GBIGBA RẸ.

| | Eko. | Ilu miran ni Nigeria. | Ilu Okere. |
|---|---|---|---|
| Ọdun kan | 12/- | 13/- | 14/- |
| Oșu mẹfa | 6/- | 6/6d. | 7/- |
| Oșu mẹta | 3/- | 3/6d. | 4/- |

Ẹ fi owo ati *Letter* ranșẹ si *Editor*.

N. V. HANDELMATTSCHAPPIJ V. H.

J. F. SICK ati AWỌN ẸGBẸ.

No. 7, Ita Ibode laiai, l' eti *Glover Memorial Hall* (*Customs Street*,) EKO





Awọn Oyinbo Onișowo yi nranșẹ MASINI-ARANSO ti a npe ni VESTA Nos. 1-4 t' ọlọwọ ati t' ẹlẹsẹ ni owo to rọju a le fi iye-owo wọn han ẹnikẹni to ba lọ si Ile-owo yi.

Nwọn mura tan lati șe adehun pataki pẹlu ẹnikẹni to ba fẹ ranșẹ Mejila tabi jubọ lọ ninu MASINI na.

Awọn Oyinbo yi nșe orișirisi Ilẹkẹ alarabara, nwọn si nranșẹ *Cement* ati panu kikọle to nipọn, ati ọja Abọmalọ ati orișirisi ọja

Ilẹkun Ile awọn Oyinbo yi și nigbakugba ti enia ba fẹ lati lọ ba wọn sọrọ ASIRI nipa OWO. IROHIN KO TO AFOJUBA.

### Ile Ita Egbogi ... Macaulay

(*Macaulay's Household Dispensary*)

A nta orisirisi ogun Ilera ni Ile-oja yi, to wa ni Opopo-nla (*Broad Street*) l'Eko ni owo no o.

Awon Ogun bi Oke, Painkiller, Ogun Inarun Ogun Lakuregbe, Ogun Kurunu, Ogun Aran to dara Ogun Eda, Ogun Areṃo.

Ogbẹni S. A. O. Macaulay enit oni Ile-Egbogi yi jẹ enit o gba Aṣẹ ogun pipo (*Certificated Dispenser.*) lowo Ijoba Nigeria.

Ẹ LỌ DAN A WO, Ogun rẹ jẹ bi idan.

---

### ỌGBẸNI J. C. VAUGHAN.

"Ti Ile-Oja Sheffield ni Ita Kakawa ati Ile-Oja "*Excelsior*" ni ita Agarawu, ni oniruru awon ohun kikole tun tita ni owo opoku-oyoku.

O ti nṣowo Irin Iṣẹ lorisirisi lati adọta ọdun sẹhin titi di oni.

ATARI AJANAKU ni ỌGBẸNI na jẹ ninu awon onisowo Irin Iṣẹ ni ilu Nigeria.

ỌKỌ tita wa ni owo po o.

---

### ỌGBẸNI DURO. THOMAS.

ONIṢOWO PATAKI.

Ti 55, Ita Faji, l'Eko, ni orisirisi Ọja to de fun u lati Ilu Germany fun tita: awọn nkan Awo abọmafọ, Cement, Akara, ati ọpọlọpọ oja miran.

Ẹ lọ de ibẹ, Igbo-Akan 'mọpa ni ohun to ni.

Bi ẹ ba fẹ, ẹ kowe si i, *Number* Apoti-Iwe rẹ ni Ile ipin iwe (*General Post Office*) ni 374. *Number* fifi-ẹrọ manamana ba a sọrọ (*Telephone*) ni 243.

---

### Ẹ WA RA ỌPỌ ỌJA.

Ogbẹni D. B. OṢUNTOLU, oniṣowo Olanrewaju ni ọpọlọpọ oja fun tita ni Ṣabu rẹ ni No. 44 Balogun Street, l'Eko.

Ninu awọn ọja rẹ ni iwọnyi:—Ikoko taba, Carpets Pann ikole, Aṣọ oniruru, Itẹko, Baranjẹ, Olowonyọ, Yọmini, (*Salien.*)

Ati orisirisi nkan atata miran, Oja Ogbẹni yi roju o si lere ninu, ọpọku-oyọku ni.

Ẹ lọ ra ti nyin nibẹ.

---

WHAT IS MORE REFRESHING than a sound sleep on a comfortable Bed? or time-saving than a thoroughly good sewing-machine?

A large consignment of Brass Iron-Beds, Bedsteads, (new arrivals from Germany.) hand and Treadle-sewing machines "Gritzner" is just to hand at Mr. Duro. Thomas's establishment 55, Massey St., Lagos.

An early call at this address for your selections will well reward your labour.

Prices attractive and alluring.

CALL TO-DAY NOT TOMORROW.

---

KILO NGBE MI LỌ YI O? ORUN!

AṢỌ NYIN FAYA, Ẹ LỌRAN.

AṢỌ NYIN FAYA, Ẹ LỌRAN.

IBUSUN-ILESANMI ati

MASINI-A-NJUWON

Ọgbẹni DURO THOMAS.

Onisọwo-towolawi, ni awọn IBUSUN mèrémèré onidẹ to ṣẹṣẹ de fun u pẹlu awọn MAṢINI iranṣọ ti a npe ni *Gritzner* ti ọlọwọ ati ti ẹ'ẹsẹ, lati ilu Jamani wa fun tita ni Ile Ọja rẹ 55, Ita Māse leti ita Faji, l'Eko.

Ifà mbẹ fun awọn to ba tete lọ ra tiwọn nibẹ: owo yẹpẹrẹ ni a nta wọn, bẹni awọn Ọja na si "ka 'yin" to.

Ẹ lọ ba Àwúre nyin pade nibẹ.

## GBOHUN-GBOHUN.

:o:

EYI A WI RE E!!!

Ni *Monday* ọsẹ yi, Adajọ kekere Ẹni-Ijuba M. C. GREEN da "seria" fun ọgọrọ awọn Ọlẹ-ba-ti-o-ko-le-kewu ti awọn Ọlẹlẹ-muyẹ ti "ra mu" ni *Saturday* ọsẹ to kọja, fun ịesun tẹtẹ ti a fi wọn sun pe nwọn nta ni ọna *Raffle*. Adajọ fi ofin de awọn alapa-ma-ṣiṣẹ na mọlẹ pẹlu pọnwun marun marun fun ẹni kọkan ni sisan si apo ọba ti wọn ba tun lu ofin na. Orukọ wọn ni a to si isalẹ yi.

1 D. J, Ọnalewu 2 Edward Adu 3 Moravọ 4 James Onipẹde 5 Abudu Lasisi 6 Samuel Macauley 7 E. A. Atẹrẹ 8 J. A. Bankọle 9 Sabitu 10 Paul Nicodimus 11 Ajayi Olusanya 12 Iṣọla Tanimọwo 13 Karimu Ayọ 14 James Kukoyi 15 Sam Ogunfowora 16 Zacheus Oguntowora 17 Kasali 18 Seidu 19 Rabiyu 20 Belo 21 O, F, Ajayi 22 David Ige 23 Adelẹyẹ 24 Raji.

OGO DE'LE IKU RẸ.

Adajọ Kotu kekere fi ọkunrin to tẹ iwe nwọn fẹ ta Ilẹ Ọba (*Government land*) to wa ni Yaba ni *Raffle* to si ti ngbowo kiri lọwọ awọn ọbọ-biyi ẹgbẹ rẹ si ẹwọn oṣu meji pẹlu iṣẹ aṣegan ni *Friday* ọsẹ to kọja.

"SAJI" OWO A FU-NA O!!!

Ọgbẹni Amos Tade Ọpẹnibọ ọkan ninu awọn Ọga Ọlọpa-Inu ti ilẹ yi gbe Iya-Afin Elizabeth Ajayi, niyawo ni *Church Baptist* ti opopo nla, ni *Thursday* ọsẹ to kọja ni agogo mẹwa arọ. Iyawo a we gele a rẹmọ o!!!

BALẸ IROKO O DI GBERE!!!

Balẹ Iroko ti o bẹ Ọgbẹni HERBERT MACAULEY C.E, ni iṣẹ Ilẹ wiwọn larin Ilu Ọyọ ati Ibadan ti ọrọ na si di rogbodiyan ni oṣu die to kọja, ku si Ibadan ni ọjọ *Monday 16th* oṣu yi, Awọn enia rẹ si wa gbe oku rẹ lọ sin ni Iroko.

ASIN-BỌRI NI IKOYI, O KU O!!!

Ni ọsẹ mẹta tabi mẹrin sẹhin ọkunrin kan ti o njẹ I I Samuel gba ọpọlọpọ enia ni Lebira (*Labourers*) o si mu wọn ṣan ibi nla kan ni Igbo Ikoyi tobẹ ti ibẹ fi mọ kedere to si dabi ọdan. A gbọ pe ọkunrin yi sọ fun awọn Lebira na pe on gba Iṣẹ na lọdọ Ọba nibi fun nkan bi Ẹgbẹdogun pọnwun (£3000,) ati pe laipẹ nkan yio "ṣenure" fun wọn. Owo ati nkan miran ti awọn Lebira yi fi fun ọkunrin na fun "ba mi ṣe" ko to le gba nwọn si iṣẹ na ki ṣe diẹ. Iyoku iregbe nigbati awọn "Akẹran" wa igi ọrọ yi nwọn ri pe ọba-irọ ni ọkunrin na pa fun wọn: wàrà-wèrè nwọn si "ra mu" iye awọn Lebira to musin lagbara lọna bayi le ni ẹgbẹrun enia (1000,) awọn wọnyi ni yio si ta ko o ni Kotu nibiti ọrọ na yio wa nisisiyi. A gbọ pe ọpọlọpọ ni yio digbese owo ti nwọn ya lati fi ra ada ati lati ṣe ãjo miran ki nwọn to le bọ sinu "iṣẹ" na.

O ṢEUN, IWỌ ỌMỌ ỌDỌ RERE.

A ba Padi Harmann ti Ijọ Aguda ni *Nigeria* yọ fun yiyan ti a yan a lati jẹ *Bishop* Ilu Aganyin ati Padi Sessou t a yan ni *Bishop* ti Ilu Togo (*Togo-Land*) ni lọlọyi.

ỌJỌ KI PẸ TITI KO MA KU ỌLA.

A bẹrẹ Ẹjọ ti awọn Ijọ *Africa* (*African Communion*) pe awọn Ijọ *Anglican* (*Anglica Communion*) ni "Ganran" lọsẹ yi nipati ọrọ Imugun ti a sọ pe Ijọ *Anglican* sọ si Ijọ *African* lara, eyiti a sọrọ rẹ ninu Iwe Irohin yi nigbati a kọkọ bẹrẹ *No. 1* Iwe na. Ọgbẹni J E Shyngle ni *Lawyer* awọn Ijọ *Africa* E O Moore Ọlọla ni aṣaju *Lawyer* ti awọn Ijọ *Anglican* niwaju Adajọ Agba Sir Ralph Combe ni a nro Ẹjọ na, Ijọ *Africa* ni nwọn fẹ gba ọgọrun pọnwun (£100) fun orukọ wọn ti nwọn baje bayi.

PAGIDA!!!!

Anu ṣe ni lati ri pe oju àgbàrá (*Drain*) ti Ọba ṣe si *Great Bridge Street*, niwaju ile Olcrogun Oloye Onifila funfun ti a ri irin wẹrẹ olori-ṣoṣoro si, ṣe alejo kan to fẹ joko si ori àgbàrá na loru laimọ lẹṣe, nitoripe awọn irin ṣoṣoro yi gun nidi, o di nkan to pa dọrun. A fẹ ki awọn Igbimọ Ilu (*Lagos Town Council.*) ṣakiyesi agbako yi.

## Obituary.

Our father ABUDU KARIMU passed away at his residence 111, Igboṣere Street Lagos, Nigeria on the 21st inst.

Mustafa Abudu Karimu, Aruna Abudu Karimu, Fosasiru Abudu Karimu, Muniratu Abudu Karimu Ti...iyu Abudu Karimu, Buraim Abudu Karimu,

## Correspondence.

Ibadan, 20. 4. 23.

To the Editor "Eko Akete"

Dear Sir,

Congratulations to our worthy friend Mr. J. Ṣitta Ṣodipọ a clerk to Messrs The Lagos Stores, Limited Ibadan a holder of 3 & 2. Pitman Shorthand Certificates who has been awarded a Certificate of F.I.P.S., and M.I.P.S., I thank Mr. Ṣodipọ for making use of his opportunity in this direction.

I wish him further success,

Yours sincerely,

OKE IBADAN.

### "ARIGBỌDỌWI."

*Si Olutwe irohin Eko Akete.*

Ojẹ ohun ti o yami lenu gidigidi lati ri ati lati sọ wiye waya "*Telegram*" ngba ijọ meta ki wọn to mulọ fun ẹniti oni. Pẹlupẹlu ẹni ti o tẹ waya si ti de ki wọn to fi jiṣẹ. Biotijẹpe waya jẹ iṣẹ kiakia "*Urgent Message*" odun ni lati ri iru aṣa bayi ni ilu. Ẹpẹ a si rope ni aipẹ ni awọn alabojuto "*Post Master General*" yio gbidanwo lati mu iru iṣẹ ọlẹ bayi kuro. Agbara-ṣabalagba ni o, ng o palaṣe o. Ki wọn si fi titaratitara ṣe iṣẹ wọn gẹgẹ bi o ti yẹ ki wọn ma wipe oko ni wọn wa.

ERO LỌNA.

"AGNUS CHAMBERS"
LAGOS,

To the Editor Eko Akete,

"More concerns about Raffle,

It is my greatest anxiety to address you frankly and express my feeling through the medium of this letter. In regard to the raffling habit which is now in existence throughout the town. I have to tell you that it has been played in England more than 50 years ago and which is still in existence and as we know that there is nothing that can come to Lagos that cannot be spoiled it will be very advisable if any suggestion can be taken against it. We know that anyone who has money may play it, but it is not good among the School Children as some use to raffle their books etc., and take their fathers' and mothers' money to play it, and by so doing bit by bit, it can lead them to ruin. The Europeans are not doing it as we are doing it for every thing has its moderation. A tin of Sardine can be raffled, now-a-days at the rate of ½d. a share and many other things. It is somewhat inconvenient to my desire in the train during my pleasant journey to Abeokuta during the past Easter holiday to see some gentlemen asking me to subscribe for this purpose but I told them that I shall never practise such mean way of stealing. A strange news comes to me that a certain woman raffled herself and she was won by a certain Liberian man in some parts of Northern Nigeria. Some gentlemen used to trade and make a good profit by this means; a Raleigh Cycle of £12 10 0, for £40, there was a well known gentleman in this town who through this practice has secured a Motor Cycle and who thinks that by this means he can gain a lot, but the result is countrary to his expectation having wasted £60. "Better it is to suffer for speaking the truth than that the truth should suffer for not being spoken."

ANTI-RAFFLER.

### ORIN NI OHUN ILẸ WA.

Iṣẹ ribiribi li o wa n' iwaju wa lati ṣe ki a to le mu aidọgba kuro ninu awọn orin ti a nkọ ni ohun ilẹ wa. Ohun ti a si ni lati kọ ṣe ni pe ki a kọ tọka si alebu ti o wa ninu awọn orin na l' eni l'eji. Mo ti tọrọ gafara ṣiwaju lọwọ Ijọ ti o ba ro pe o gbun leti wọn lati fi tifẹtifẹ gba a.

Kakiri gbogbo Ijọ ti a nkọrin ni ohun ilẹ wa pẹlu Batakoto ati ohun elo ilu miran, ni a ri wipe a ufẹ atunṣe, nitori wipe ariwo ilu ko kere, ati pẹlu pẹ, ninu gbogbo awọn orin na

ti a nkọ, gb'ẹsẹ at'ẹjika soke jo niwọn. Laisi ani-ani, o yẹ ki a ni ǒrişirişi orin pẹlu ohun *tune* kikọ fun oniruru igba—akoko ayọ tabi aro, awẹ tabi idaraya, a si nfẹ awọn orin ti a o le ma pin ẹla (*Time & beats*) rẹ si ọna meji, mẹta, mẹrin tabi mẹjọ.

Alebu ti o wa fun awa enia dudu ni pe a ki i lakaka lati wa ilọsiwaju ohun ti a ba dawọle ni şişe. Nigbati, Ijọ *Aethopia* bẹrẹ pẹlu Batakoto Duru ati konkolo, Ijọ *Brotherhood* tẹwọgba aşa kanna laisi iyipada fun ilọsiwaju bẹ gẹgẹ ni Ijọ Idapọ Ọmọ Ibilẹ *African Comunion.* Ẹnikẹni ti o ba lọ si Ijọ *Aethopia* l'akoko ti nwọn nşe isin ni igboro Eko ti o ba si lọ si Ijọ *Brotherhood* tabi Ijọ Idapọ Ọmọ Ibilẹ yio şakiyesi pe eto ati işarasi lu ilu ati kikọ orin nwọn san ju ti Ijọ to ku lọ. Ibaşe ni Ijọ *Brotherhood* tabi Ijọ Ọmọ Ibilẹ, batakoto pẹlu orin kikọ wọn dabi igbati a pejọ fun ariya. Gbogbo orin ti a si nkọ ninu awọn ijọ wọnyi li o ni ijo bọni.

O yẹ lati sin Ọlọrun pẹl ohun elo ti ilu wa şugbọn kini şe ti a o fi duro ti Batakoto nikan pẹlu itẹlọrun?

OYENEYE.

[A fẹ ki Oyenẹyẹ mọ pe şaşa ni orin Yoruba ti ko mu Idaraya dani. Enia le kọrin daraya lalaiñ ijo bọ ọ. A si tanmọ pe Isin Ọlọrun ko mu ọfọ şişe tabi oju fifaro dani.

O ha jẹ pe Ọrẹ wa yi gbagbe Ọrọ iyebiye ti St. Paul sọ pe:

"Ẹ ma yọ ninu Oluwa nigbagbogbo mo si tun wipe Ẹ ma yọ"—ED. E.A.]

## The Brotherhood Christian Church

ANNUAL ELECTION 1923—1924.

MINISTERIAL AND INNER CIRCLE.

Pastor, A. Adedeji Işọla, F.B.P.I., M.V.O.M.,
*Founder and Superintendent.*

Prof. Adeoye Deniga,—*Assistant Superintendent.*

APOSTLES.

A. Gbogboade Esq., S. A. Coleman Daniel Esq.,
Fagbemi Faşeyi „ Gabriel Ogunlẹye „

LOCAL PREACHERS.

A. Ibaru Esq., A. Ọkọya Esq., D. A. Adesanya Esq.
J. A. Davies, Esq E. A. Adegun, Esq.
J. R. Turton, Esq. J. A Domingo, Esq.
Daddy Adebọgun,

HON. LAY READERS.

A. A. Tuakley Lawson, Esq. A. Gbogboade, Esq.

HONORARY.

*Patron*—Dr. O. Şapara

*Vice Patron*—I. E. Abraham, Esq.

(*To be continued*)

## FẸSỌ ŞE O, KO MA BA DARIWO.

Lati igba ti awẹ ti bẹrẹ ni ati ni lati şe suru atipe nisisiyi suru na wa di suru, nipa ti awọn Imale wa ti wọn sọ di aşa lati ma ji lu ilu ni agogo mẹta abọ araro titi di agogo mẹfa arọ. A ko sọ pe nipa aniyan wọn lati ji wọn, eyi buru, şugbọn ohun pataki ti a fẹ tọka si ni pe awọn ọmọ wọn sọ di aşa lati ma lu ilu yi kakiri pẹlu orin alufaşa lẹhin ti a ti pe isin Ọlọrun ni a nsin. Igba pupọ ni awọn ọmọde wọnyi ma nfi dẹ gàngàn tẹ kokorọ bọ orin-işa wọn, niwaju ile onigbagbọ pẹlu ebu ti *ko* i to ti ko yẹ eyiti awọn baba wọn iba fi şe şai, wọn a ma wipe şe "ọmọde ni wọn" bẹni wọn mọ pe eyi ko tọ suna ninu isin Anabi Mohamed, kini şe l koi to fun awọn Imale Eko lati mọ pe iwa ilu pẹlu orin-korin yi ko yẹ işin tabi oju wọn koi la to ni ti wọn ba şe akiyesi wọn o ri awọn Onigbagbọ pe "ori ni wọn npe ori ati pe Ẹsẹ si jẹ ẹsẹ." Opọlọpọ awọn Imale ti mo ri lo nşata awọn Ahmadia, mo şe akiyesi pe awọn enia wa papa lo nba isin wa jẹ nipa gbigba awọn ọmọ wọn laye iwa ipata lati kekere lọ. Ẹnikẹni ti o ba lọ wo gẹgẹ bi awọn Ahmadia ti nşe isin wọn ati eto pẹlu ẹkọ ti wọn nkọ awọn ọmọ wọn yio ri pe ilaju wa ninu isin wọn ju eyi ti awọn Gambari muwa fun awọn enia wa. Mo tun şe akiyesi owe awọn baba wa pe "Imale Isalẹ Eko bi oni şango Olowogbowo" mo fi ara balẹ lati wa idi owe yi mo si ti ri pe otọ papa ni.

Lati igba ti awẹ yi ti bẹrẹ ti awọn ọmọ Idunmagbo lo lẹ ju kaka ki wọn dioka şişe ni upele si. Tulasi o fẹ o kọ o nilati ji ni agogo mẹta abọ ti wọn ba ti jade pẹlu Bẹmbẹ ati Ọrun-işa wọn. Danwo lati kilọ fun wọn wa gbọ ipọri ararẹ pẹlu ebu oniruru, eyi mu ni gbagbọ pe owe awọn baba wa tọna toto. Ninu gbogbo awọn Alhaji to nşe wasi nko gbọ pe ilu ni nkan pataki ninu isin Imale ni *Mecca*, nitori eyi abẹ obi awọn ọmọde kekeke wọnyi lati kilọ fun wọn pe owo ki fun owo lọrun ki nwọn ma şe mẹlọ mẹlọ ko ma ba di ariwo.

Ironupawada ti ẹ ntọrọ ki Ọlọrun na le jẹ ni ẹ ri otitọ ninu rẹ.

AKIRIMANU.

**EKO AKETE:**

Eko, Saturday, April 28, 1923.

## OYI-BIRI GBOJU-ỌNA-KAN-KAN, KAN OKỌ TẸJUMADE! AKODU MADA, ỌKỌNRIN-TA-FI NṢEPE ỌKỌNRIN, ỌRUN A GBE Ọ!!!

Ilu rọ kẹkẹ ni *Sunday* to kọja nigbati a gbọ pe Daddy Michael Daniel Elliot ẹniti apele rẹ njẹ Akodu, tẹrigbaṣọ lalẹ ọjọ na ni ile rẹ loke Olowogbowo.

Bi omi ni enia nwọ lọjọ keji nibi oku na, lati lọ wo Posi Ọgbẹni-Olowo-soke-dilẹ yi, ti a gbọ pe o ti ranṣẹ fun ni ilu Oyinbo fun £95 niwọn ọdun mẹtadilogun sẹhin (1906 :) nigbati a si fi oju "ganni" rẹ, a ke "Safula" fun okuru Idẹ ti a fi ṣe e. Biotilẹjẹpe owo ati dukia Ọgbẹni na "buaya" sibẹ, ẹru iku ko fi igba kan ba a ri, mbaṣepe ẹru iku ba a ni, ki ba ti le ṣe nkan ribiribi ti pupọ ninu awọn ojo olowo miran ko jẹ ṣe, eyini ni riranṣẹ fun "ibi-isimi ikẹhin" rẹ, nigbati o ṣi wa laye : ẹkọ ribiribi leyi fun tọmọde tagba wa.

Nigbati Ọgbẹni na wa lorilẹ, a sọpe o ma "nsaba" a ndubulẹ sinu Posi na lẹkọkan ti yio si wa ninu rẹ fun iwọn iṣẹju pupọ, to njẹ faji nibẹ, tobẹ ti a wipe nigbati o dubulẹ sinu rẹ lọjọ kan. gẹgẹ bi aṣa rẹ lati ẹhin wa, ọmọ-ọdọ rẹ kan to jẹ alawada enia, ṣugbọn to ti di bale-ile nisisiyi, sọ ọ pe ki o jẹ ki on kuku ṣe Ọgbẹni na sipa rẹ lẹkan, nipa pe ki o fun on laṣẹ lati fi ọmori Posi na de e, ki on si kan a pa!!! A ko le ṣẹṣẹ ma tọ pinpin esi ti yio jade lẹnu Alagba na si irufẹ ibere ẹwọ na nitoripe Daddy fọnmu, tani njẹun, t' aja njuru, ina njo, o nfẹ?

Ile Isin ti Olowogbowo (*Wesley* :) ni a gbe oku na lọ ni *Monday* ọjọ keji, lẹhinna o di Ikoyi rẹrẹ lọjọrọ *Monday* kanna, ti *Motor-Car* npe *motor-car* ranṣẹ, kẹkẹ-ologere ati ti afọwọwọ iyẹn ainiye. Alufa Agba Ẹni-ọwọ A. N. Cole pẹlu Ẹni-ọwọ E. E. Williams ati S. A. Pearse lo "ṣe etutu" igbẹhin toku ni Ikoyi, enia lọ su u lọjọ yi.

Mrs. Priscilla Elliot, Ọgbeni Albert Elliot, ati Ọgbeni Daniel Elliot, ti o ba iṣẹ-ọba lọ si Onitsha nisisiyi, Mrs. Ellen King, Miss. Flora Ibidapo Elliot, Mrs. Ẹbun Vaughan, Miss. Minne Elliot ati ẹnyin ọmọ-oniku toku ati iyekan oku, a ba nyin kẹdun gidigidi fun ọfọ yi, Ẹ ku Afẹku!!! Baba ko ku, nṣe lo pa-ipo da.

A sọ pe Posi ti ẹniti o tun larinrin bi ti Alagba yi ni ti Ọgbẹni "Saro" kan ti a npe ni "Abuke" Thomas, nitori fadaka ti a ni a fi gba a yikayika, pẹlu ehin-erin lẹgbẹ ọtun ati ni tosi, ni ilu Saro : a gbọ pe ọgbẹni yi lowo tobẹgẹ ti o fi ya Ijọba *Gambe* ni £80,000 ọkẹ mẹrin pọnun lakoko kan nigba aiye rẹ: Enia Dudu ni Igi-owo na.

Kẹlẹkẹlẹ awọn Alagba wa nfi ilẹ silẹ leni-tere, ejti-ere. Ẹhin wọn a dara, Ologbe na jẹ *Trustee Church* rẹ (Olowogbowo.)

Njẹ Ọgbeni Michael Daniel Elliot, o di arinna ko, o di oju ala firi, o d' oko alawo!!! Ki baba fi aṣiṣẹ rẹ ji ọ, ko si gbe ẹ s' fẹfẹ rere.

Gẹgẹ la o gbe e,
Oku Ọlọmọ, gẹgẹ la o gbe
Eyiti o lọmọ, gẹgẹ la o gbe e,
A f eyi 'o l'ara,
Gẹgẹ la o gbe e!!!

---

## ỌDUN ỌDUN NI ỌDUN RE!

Ayọ pupọ lojẹ fun awọn Imale Eko to ni ero lori lati pe Awẹ bẹrẹ larin wa laisi Ija. Ko si iwa te mi ni yio ṣẹ tabi ti ẹnyin ni yio ṣẹ. Iwa ti o sọ gbogbo awọn Imale Eko di yẹpẹrẹ. O han gbangbangban fun wa pe ilaju de si arin wa eyiti o le mu Isin lọ si wa ju.

Awọn Imam meji pataki yi Buraimo ati Mọmodu Dabiri pẹlu olori awọn Ijọ to ya lọ si Okepopo, lagbọ pe nwọn kede awẹ fun awọn Jama'a wọn, pe awẹ o yio bẹrẹ ni ọjọ Atalata, awọn enia wọn si fi tifẹtifẹ gba ọrọ na laisi ariwo Ija nwọn sin bẹrẹ awẹ na pẹlu irọrun, nwọn jẹ sari pẹlu alafia, wọn si gba awẹ, lagba gbadun. Ọkan wọn sin bọsi ọkan kan gan lati sin Oluwa Ọlọrun wọn.

A dupẹ lọwọ awọn Imam wọnyi ati Olori Ijọ Okepopo.

Ajilaran.

# SINGER ! SINGER !! SINGER !!!



Kinla ! Tiwa ki nṣe a nṣẹṣẹ wa onibara, kini a ti nṣ'oku l'ọrun, nwọn pọ to wọ... larin oriṣiriṣi enia jakejado Nigeria.

Ẹrọ iranṣọ " SINGER " kọkan, ni gasikia polowo ara rẹ.

Pataki ohun ti o mu ' Ẹlẹha jade ọsan ' ni wipe a nfẹ mu wa si akiyesi awọn ogun onibara wa

TI ẸDINWO NLNLA TI A ṢE

ninu owo ẸRỌ IRANṢỌ wa ati IRIN-IṢẸ wọn, eyiti o fẹrẹ ba iye owo ti a nta wọn ki ogun Jamani to bẹrẹ nijelo mu.

wọnyi ni diẹ ninu awọn ohun pataki ti o jẹ ki ẸRỌ IRANṢỌ SINGER t'idi awọn ẹrọ iranṣọ miran b'omigbona.

Ikinni.—Ẹwa, itẹju ati idakẹ rọrọ l'ẹnu iṣẹ.

Ikeji.—Irọrun ti o wa lati ri oriṣiriṣi irin iṣẹ rẹ ti o ba bajẹ ra.

Iketa.—Ifọwọsọ'ya lati tun gbogbo Ẹrọ Iranṣọ 'SINGER' ṣe nigbakugba l'ọfẹ ibaṣepe a ra lọdọ wa tabi ni Ẹka-ile ọja wa miran.

Wa bere iye owo wọn ni Ile-ọja wa ni Popo nla l'eko nibiti ' Ẹrọ Oyibiri ' nl'agogo.

Phone L222, Extensions 2 & 3.
P.O. Box 171.

DADA ADESHIGBIN & SONS,
*Sole Importers Singer Sewing Machines.*



ỌGBẸNI OYINBO ONIṢOWO

***R. A. JAMESON***

Ti Opopo-Nla

Ni Iyọ to funfun bi Lekeleke fun tita ninu Apo ogoji Iwọn, £5 10 o lo nta a fun *ton* kọkan Ọrẹ, lọ sibẹ, maṣe jẹ ọbẹ obu o !


## To whom it may Concern.

The Public is hereby notified that Mr. B. O. JOSEPH of 64, Breadfruit Street, who had wanted to Raffle his Motor Car has decided not to do so again and has instructed his Driver who carries the list about to refund money to those who have paid.

Lagos, 13th April, 1923.

"ELETI-QFẸ" ṢẸ IGI ERA.

EK IWQ, IWQ NI YIO PA ARA RẸ !!!

Aye ko si fun wa rara lati ba "gbo ja wùrà" nipa fifa ọrọ ijiyan Bishop kọṣe Bishop eyiti oniwe-irohin Eleti-Ọfẹ da silẹ tun ara rẹ lẹnu ọsẹ diẹ sẹhin: ọrọ ti o si sọ sinu iwe rẹ na ti ọsẹ to kọja jẹ ọrọ-abi-ikọ patapata, ti a ko nireti pe ẹnikẹni ti o npe ara rẹ ni nkan gunma ninu oyé iwe ati ọmọluwabi le sọ, ayaṣebi ọmọ ti a ko ba gbe ra ina: ọrọ ti oniwe-irohin yi si sọ ninu Iwe-irohin rẹ lọsẹ yi ti o npe ni esi jẹ aroye-ọtẹ jakejado: Ti gbolohun kan ni bi elepo, elepo ni ṣe gbọ -nran:" nigbati Ọgbẹni na ti le sọ Ẹgbọn ko ka Iya-enia-si-mimọ (Consecration) si fun iṣẹ Ọlọrun npa titu Ororo Safiọ si oluwarẹ lori, nigbana ni o ti jewọ ... ko ri oye ohun ti a bere lọwọ rẹ o nti atamọ, mọ atamọ ni kosi ye, ko ya ẹnikẹni lẹnu fun esi yi, nitori Ọgbẹni oniwe-irohin yi si wa ni oko eru ni, nipa Isin-Ọlọrun Iọna Kristi, on ati awọn ti o nro bi rẹ ni orin yi yẹ, "Ẹ pe Enia Dudu wa'le, Ẹ pe wọn wa'le," (Emi-ọwọ S. A. Oke, mo tọrọ gafara orin yi lọwọ rẹ o.)

Ko di igbati a ba ṣeṣẹ lọ ṣe jẹjẹ-korodo lọdọ Archbishop ni England fun oye Bishop ki a to jẹ Bishop: O ma ṣe o! anu Ọgbẹni oniwe-irohin yi nṣe wa nitoripe ko mọ Itan Church ti o wa (he is a mere Zero in Church History.) A fẹ ki o lọ ka Article 34 ti Church of England eyiti Anglican Church ti oniwe-irohin yi nṣe member rẹ, jẹ ẹya rẹ: a si fẹ ki o lọ ka awọn ọrọ wọnyi ninu Bibeli rẹ, eyini ni ninu Testament Titun.

(1) I Peter ii. 25. (2) I Tim. iii. 1 & 2. (3) Acts xx. 28. (4) Phil. i. 1. (5) Titus i. 7.

Ni tiwa, Bishop ti Bibeli (Bible Bishop) ni Bishop G. A. Oke nṣe faufau, laisi tabi-tabi ninu rẹ: O le ma jẹ bẹ ẹ loju awọn Aladamọ ati awọn Alagbata-to nsọja dọwọn, ṣugbọn, loju Kristi ati Olodumare pãpã, Bishop ni Oke nṣe gẹgẹ bi itumọ rẹ ti wa ninu Ede Greek ti a fi kọ Testament titun, eyini ni Episcopus tabi Presbuteros itumọ rẹ ni Overseer, Superintendent, Alabojuto.

Bishop G. A. Oke, gbere rẹ ẹ ẹ!!!

A fi opin si ọrọ ijiyan yi ninu Iwe-Irohin wa yi lati oni lọ.

Ed. Eko-Akete.

---

## Lagos Town Council.

AKIYESI FUN GBOGBO ENIA.

A kede nihin pe yiyan Enia si Ajọ Igbimọ Ilu Lagos Town Council yio wa ni ọjọ Asibi Saturday ọjọ keji oṣu June, Ọdun yi.

A o ṣe iyan enia na ninu Ile Ere ni Ẹhin Igbẹti, ti a npe ni Glover Memorial, to fara mọ ile owo nla Bank of British West Africa Limited.

Ẹnikẹni ti o ngbe ile ti a nsan ṣile mẹdogun lọdun fun owo omi, tabi jubẹlọ lori ile na, ti orukọ rẹ si wa ninu iwe awọn ti o le yan enia si Ajọ Igbimọ Ilu, Lagos Town Council yio ni agbara lati daruko ati lati yan enia ni ibiti a o ṣe ipade na.

Ki a to le fi orukọ ẹnikẹni ti o fẹ ki a yan on sinu iwe enia mẹta ninu awọn ti orukọ wọn wa ninu iwe Ayani yio darukọ oluwa rẹ sinu iwe, ki agogo marun to lu ni ọjọ kẹkandinlogun oṣu May (19th May.)

Yinyani enia yio bẹrẹ ni agogo mẹjọ owurọ yio si pari ni agogo mẹrin alẹ ọjọ na, gbogbo awọn ẹniti o ba si nfẹ ni ọwọ ninu rẹ ni lati wa si Ile Ere ni Ẹhin Igbẹti na, Glover Memorial Hall larin agogo mẹjọ owurọ ati agogo mẹrin oju-alẹ.

Ivor C. Watton,
*Adele Akọwe Igbimọ Ilu.*

*Ọjọ kejidinlogun oṣu April, 1923.*
*Eko,*

## All for Bicycles and Motors.

Ask for KADUNA STORE,
No. 81, Ọdunfa Street,
Near the Famous Building of
Mr. Andrew Thomas, Lagos.
*At reduced prices*

Special Dunlop Bicycles Tyres Beaded-edge 12/-
do. do. 15/-

The above Tyres are specially for Rudge-withworth and German Cycles and we have complete workshop for repairing of all kinds of machinery. Send all your repairs' Bicycles, Motors, Sewing machines, Gramophone, painting, enamelling work soldering, etc., to the Properitor at the undermentioned address. All Bicycles spare parts on sale.

SAM. A. CLAY,
No. 1 Macauley Street,
or at Workshop, 81, Ọdunfa St.
Lagos.

*Telegram Address:*—KADUNA STORE,
81, Ọdunfa Street,
Lagos.

## Lagos Town Council.

PUBLIC NOTICE.

Notice is hereby given that the Election of Members to the Lagos Town Council will take place on Saturday the 2nd June, 1923. The election will be held at The Glover Memorial Hall, the Marina.

Any person occupying a tenement assessed at £5 per annum or more whose name appears on the Voter's List is entitled to vote at the Election.

Every Candidate for Election must be nominated in writing by three voters before 5 p.m. on the 10th May, 1923.

The Voting for Candidates will commence at 9 o'clock a.m. and close at 4 o'clock p.m.

IVOR C. WATTON,
*Acting Secretary, Town Council.*

Dated 16th April, 1923.

## The Philharmonic Band.



Awọn oni fere yi nfun pẹtẹ, ilù nwọn si dun bi oyin l' eti.

Owo ti a nfi pe nwọn ko pọ, nwọn ko si kọ̀ lati lọ si ilu ki ilu,

Ẹni ba fẹ nwọn, ko kọ iwe si,

*THE SECRETARY.*
c/o Anfani Motors
The Marina Lagos.

"KỌ-OGE-NIWẸ" SEWING INSTITUTE,
119, TOKUNBỌ STREET. LAGOS.

MRS. FRANCES ADEYEMI THORPE (NEE GREEN) K'ogeniwẹ, a fi iṣẹ ni lapa ṣe fuja, bẹrẹ si Iṣẹ Ọna rẹ ni No. 119 Tokunbọ Street. Ni ti aṣọ riran ni aṣa oriṣirişi ko ni ẹgbẹ.

Ẹyin ọmọge ti nfẹ iṣẹ kọ, Ẹ lọ ri i.

## DRESS-MAKING.

"KỌ-OGE-NIWẸ" SEWING INSTITUTE,
119, TOKUNBỌ STREET, LAGOS.

If you want a perfect fit and artistically made dress, patronize the above institute and you will be amply satisfied.

Girls requiring tuition in the modern and up to date style of Dress-making please apply to the above Institute.

*TERMS MODERATE.*

## "O ṢE' WỌ NI!" (FAIR WARNING)

Ọgbẹni A. W. Olukolu Onigbanjo to gba Aṣẹ lọdọ Ijọba *Nigeria,* nta oriṣirişi ọja ni Gbanjo, nile Gbanjo rẹ ni 2, Isalẹgangan Street, l'Eko.

O si nta ile ati ilẹ pẹlu.

Awọn ọjọ ọja-tita ni iwọnyi. Monday, ati Thursday, lagogo mẹta ọsan. Saturday, lagogo mẹsan arọ, lọsọsẹ. O ntete san owo ọja fun enia. Mu ọja rẹ lọ si bẹ

## Preachers for To-morrow.
AWỌN ONIWASU ỌLA.

ROMAN CATHOLIC (HOLY CROSS)

Masses will be sung by Priests appointed. Awọn Paddi ti a yan yi o ṣe Isin ni gbogbo akoko wọnyi. (MORNING)

Masses Isin Arọ.
6.30 7.30 8.30 9.30
7.30 8.30 9.30 10.30.

(EVENING.)
Masses (Benediction) Isin Ibukun.
4.45—5.30 6.45—7.30.

ST. MICHAEL'S (Lafiaji.)
MORNING. 7 a.m.—8 a.m. 8.30 a.m.—9.30 a.m.
EVENING. 5.45—6.30 p.m.

ANGLICAN

| Time. | | Preacher. |
|---|---|---|
| 9 a.m. | Christ Church | The Vicar |
| 6.30 p.m. | do. | do. |
| 9 a.m.— | St. Paul's (Breadfruit) | Ven. Archdeacon T. A. J. Ogunbiyi. |
| 6.30 p.m. | | do. |
| 9 a.m. | St. John's (Aroloya) | Rev. H. V. E. Johnson |
| 6.30 p.m. | do | do |
| 9 a.m. & 4 p.m. | St. Peter's (Alapako) | Rev. J. A. Cole |
| 9 a.m. & 6.30 p.m. | Holy Trinity (Ebute Ero.) | Rev. S. J. Gansallo |
| 6 a.m.... | St. David's (Jordan) | Rev J. A. Leigh |

WESLEYAN

| | | |
|---|---|---|
| 10.30 a.m. | Tinubu | Rev. A. N. Cole |
| 7 p.m. | do. | do. |
| 10 30 a.m. | Ereko | Bro. J. Ayọ Coker |
| 7 p.m. | | Rev. D. A. Bababunmi |
| 10.30 a.m. | Olowogbowo | Rev. E. E. Williams |
| 7 p.m. | | Rev. S. A. Pearce |
| 10 30 a.m. | Ọbun Eko | Rev. S. A. Pearce |
| 7 p.m. | | Bro. Samuel O. Taiwo |

AFRICAN (COMMUNION)

| | | |
|---|---|---|
| 9 a.m. | Jehovah Shalom | Bro. S. P. Ọbalade |
| 7 p.m. | | Rev. J. F. Ogunko |
| 9 a.m. | Erelu | Bro T. O. Johnson |
| 7 p.m. | do. | Bro. J. A. Lalẹyẹ |
| 9 a.m. | Bethel | Rev E. A. Akinọla |
| 6 30 p.m | | Rev. T. O. Oyekunle |
| 9 a.m. | Zion | Bro. E. A. T. Fayan |
| 6.30 p.m. | do. | Bro. Gabriel Coker |
| 10.30 a.m | African Methodist | Rev N. J. D Ṣomuji |
| 4 30 p.m. | | Bro. A. T. Iroko |
| 9 a.m. | Ararọmi (Baptist) | Rev. A. A. Puddicombe |
| 4 p.m. | | do. |

EBENEZER (BAPTIST)

| | | |
|---|---|---|
| 9 a.m. | | Rev. E. C. Alabi |
| 6.30 p.m. | | Bro. Joseph Bandele |

BROTHERHOOD

| | | |
|---|---|---|
| 7.30 a.m. | Ilupesi | Prof. Adeoye Deniga |
| 7 p.m. | | Pastor A. Adedeji Iṣọla |

ST. STEPHEN'S (EPETEDO)

9 a.m. & 4 p.m. Bro. Thomas Akajagbo

AHMADIA (ISLAM)

6 a.m. Fajir Service Y. P. O. Ṣodẹyinde
5.30 p.m. Open Air Service Imam K. R. Ajọṣẹ (Bamgboṣe Street.)

COLONIAL CHURCH. (ODAN)

8 a.m.—Holy Communion
6.45 p.m.—Evensong and Sermon Rev. H. A. Lewis

SALVATION ARMY.

Services at Glover Memorial Hall, 10 a.m. and in the Streets.

---


SIMENTI NYAJU !!!

Ọgbẹni Mumuni Ainde ti No. 27, Ita Massey L' Eko ni ojulowo *BIRIKI* fun tita fun ẹnikẹni, owo wọn si rọju.

Ẹnikẹni to ba nfẹ ba Ọgbẹni na ra awọn *BIRIKI* yi le lọ ke si i ni adugbo rẹ.

Ki a ri uyin o, Ẹnikeji, Ijafara lewu.

---

W' O BI, ẸNIKEJI, OJU L'ỌRỌ WÀ!

Maṣini Aranṣọ ti a npe ni "MUNDLOS" wa fun tita niti Ọgbẹni J. S. JOHNSON ti 16, Ita ọja Ajaṣẹ, ati ni Ṣabu ALAJI MASU ni Ita Agarawu ni owo ọpọku-ọyọku

Ni Ile-iwo oriṣiriṣi ọja ti Ọgbẹni ARNOLD SCHLESINGER, Oniṣowo ara Jamani ni Ita 7, Labinjọ, leti Ita William

lẹ gbe le ri awọn ẹrọ RECORDS ohun orin ijọ to ṣẹṣẹ de ra ati awọn Ẹrọ wọnyi.

Ẹrọ ohun-orin GRAMOPHONE
Kẹkẹ-olo-gere BICYCLE
Awo Abọmafọ ENAMELWARES
Waji BLUE ati ogunlọgọ ọja miran.
Ẹ sure tete lọ ra ti nyin nibẹ.

**Mo gbe tana danu Mo gbe miran de.**

Ile Egbogi ti a npe ni Ise Olodunnare ti o wa ni egbe Ile Oloye Aromire ni Obun Eko, kun fun orişirişi awon Egbogi wonyi ti o şeşe de :—

Egbogi Kunnan ati Oşe re, Egbogi Isaka, Jedijedi, Ela omode, Iba, Ipa orere omode, Egbogi Eda ati Aran Kinisa, Egbogi Inu riru iwaşu, ati fun okunrin peIu, egbogi ki ara okuntin le giri (ko mi ye e) ati orişirişi awon eyiti a ko le darukọ tan.

Sare lọ sibẹ, ki olora tire, opokaoyoku ni, bi o fe lori, oma dowo re o,

"Arun ma jogun, ndagba si eleda re."

JOSHUA O. ADE: CRAIG,
*Alabojuto.*

116 Great Bridge Street,
Ita Onikoyi, Idunmota,
Lagos.

---

"EKO AKETE."

A le ri Iwe-Irohin yi ra lodo Aşoju wa.

Ajenifuja Stores, 109 Broad Street, LAGOS.

Ogbeni VIDAL R. COLE.

---

**WHY LOOKING SAD ?**

Are you impotent, suffering from sexual weakness, nervous prostration or loss of memory why don't you use Mutracitoin and get instant relief. It will rejuvenate you, and restore your youthful energy. Its effect is wonderful and permanent. No matter how Chronic your case may be. It is also unsurpassed remedy for women in case of barreness, irregular Menstruation sexual Neurasthenia etc., etc. In order that every sufferer should have a trial of this valuable Medicine the prices are reduced for only limited time at 4/6 in bottle of 50 pills and 6/6 in bottle of 100 pills obtainable at "Ajenifuja" Store No. 109 & 111, Broad Street.

VIDAL R. COLE,
*Sole Agent.*

---

**FIRST CLASS TONSORIAL ARTIST.**

Mr. A. L. KOSOKO the well-known Barber late of Customs Street, Lagos, begs leave to inform his many clients of his new Establishment at 135, Victoria Road, this City, where prompt attendance will be accorded them as heretofore.

Razors, Combs, Perfumes, etc, are also on sale at prices to suit everybody.

Call or send ; warm wellcome to all.


NOTICE.

When replying advertisers, please mention "Eko Akete"

---

AKIYESI.

Ti e ba fe lọ si ọdọ awon ti o polowo oja sinu Iwe-irohin yi, e jare e so pe ninu iwe-irohin Eko Akete ni e ti ri ipolowo oja na ki.

---


**First Class Dressmaking!!!**

Mrs. ABRAHAM ASHAER trained in Paris, begs to offer her professional services to the public.

Latest modes at moderate charges satisfaction gauranteed. Call at once at

117, Victoria Road,
Lagos, Nigeria.

---

**PAGIDARI!**

*Olokiki* S. FRANCIS LAWANI *Saka-jojo.*

Onişowo ni Victoria Road ni wibi-wosi ohun elo, fun Omoge ati Omode-m'eşo ti o si nta ni ita oloko o-gbowo.

O si tun ni aye pataki kan ninu ile oja na, ti a nşe Gbajamo fun ni, ni owo-ti-kotani-lara, bi şile kan, sisi, tabi toro.

Egbogi orişi-rişi iwosan oniruuru aisan, Ipara olo-orun, ati agborun Jigin-oju, ati nkan meremere po to wobu nibe.

Ikan-o-jokan irin işe ati Egbogi ti a fi nya *Photo* aworan wa nibe ni opoku-yoku.

Oniru-nru wosiwosi ti a ko le ka tan po nibe bere ohun-ko-hun ti o ba nfe yio pese re fun o.

O ngbero laipe, lati şi ile Ero Idan Awoşeju ti a npe ni *(Cinema)* ni Great Bridge Street, Iduumagbo.

Şoroko a gbe şeranwo ni igbati o ba şi ibe
Irohin ko to afojuba.

*P.O.Box 159* *Phone 214*

## ALASE LEATHER FACTORY.

"ILE ALAWỌ."

Sole-Leather tanned in a most modern style and Upper-Leather prepared in all colours, namely:—Black, White, Red, Yellow and Green, are obtainable at very cheap prices.




Awọ Bata ni ọpọku ọyọku. Kọwe ṣọwọ yala ni ede Yoruba tabi ti Gẹsi pẹlu owo si:—

E. B. BEYIOKU-ALASẸ

108, Moloney Bridge St.

P. O. Box 568, Lagos, Nigeria.

*Telegrams*:—Alawobata, Eko.


### CHANGE OF NAME.

I Michael Adol Martins formerly known and addressed as above, beg to inform the public in general that from and after 1st day of April, 1923, all letters documents, should be addressed to me as ADEYẸMI OṢONARIWO.

Any letters or documents, bearing the former name before this date remain valid.

ADEYẸMI OṢONARIWO


## AWỌN IWE ỌGBẸNI J. G. KUYẸ

Fun Ile Eko.

| | | |
|---|---|---|
| A. B. D. Alaworan | ... | 3d. |
| Iwe Alaworan Kini | ... | 7d. |
| Iwe Alaworan Keji | ... | 9d. |

Awọn iwe wọnyi ko ti si lode ni sa kan nitori ogun Germani, ṣugbon wọn fun de nisisiyi, a si le ri wọn ra ni Ile Iwe tita ti C.M.S ninu ilu yi tabi lehin odi.

Itan ati owe ti o wa ninu iwe wọnyi dara pupọ, bẹ gẹgẹ ni awọn aworan inu wọn dara fun ọmọde to, ẹniti o ba dan a wo yio ri pe ọgbọn ẹniti o ti jẹ oluko awọn ọmọde fun ọdun pupọ li a fi ko awọn iwe na lẹsẹsẹ, kiṣe iṣe *ṣire ibaje*.

A le ri awọn iwe wọnyi ra pẹlu kolo oniwe ni ẹdin owo, 60, Ibadan Street, Ebute Mẹta.

## GIDIGBO! GIDIGBO!! HEYA!!!



Awọn RECORDS to nkọrin lede YORUBA pọ to wọbu ni ile owo.

MANN POOLE & COMPANY LTD.

8, TINUBU SQUARE, LAGOS.

Ki la ti nṣ' oku l' ọrun?

Ki la ti nṣ' ori nile Iku?

Tutu tabi Gbigbẹ?

Ọpọkuyọku si ni, wa ṣa eyi to wu ọ ni:—

8, TINUBU SQUARE, LAGOS.


PRINTED AT "TIKA-TORE" PRINTING WORKS, 20, MARKET STREET, LAGOS, AND PUBLISHED BY ADEOYE DENIGA AT 24, WILLIAMS STREET, LAGOS, WRITER AND LECTURER.